

# EYI NI ỌJỌ AWỌN ỌJA ILẸ WA.

### ỌJỌ AJE 10TH SEPTEMBER (MONDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Mushin Badagry |
| Abẹokuta | Otta, Abalabi, Ṣodẹke, Owode. Omida Ilawo Owowo Obatemi |
| Ibadan | Oja-Oje |
| Ijẹbu | Ikenne Okunowa Erunwon Mamu, Omu |
| Ijẹsha | Ijẹbu-Ijẹsha, Osu, Itagu, Idoko Iloko Odogbo, Owode |
| Ondo ati Eti Odo | Ishua, Aye Erinkẹia Agbabu Igbogi |
| Egbado | Ilobi Igbogila Ijoun Imasai |
| Ogbomosho | Araromi Iregba |
| Ekiti | Erekesan |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajọ | Iloro |

### ỌJỌ AJE 11TH SEPTEMBER (TUESDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Agege Ikeja |
| Abẹokuta | Lafẹnwa Obada Oba Kajola Ajẹgunlẹ, Idogo, Ogunmaki |
| Ibadan | Lalupon Ibuko |
| Ijẹbu | Isara Imodi, Ibẹfun Atikori Imushin Ago-Iwoye Ijesha-Ijẹbu |
| Ijẹsha | Esa Oke Iwara Ejioro Odo Ibokun, Esa-Odo, Eti Oni. |
| Ondo ati Eti Odo | Igbo-Egunren |
| Egbado | Idi-Omi Lasilo Igan-Okoto Atta |
| Ogbomosho | Oko |
| Ekiti | Ifaki Okemesi |
| Ibinni | Uromi |
| Delta | |
| Igbajo | |

### ỌJỌ 'RỌ 12TH SEPTEMBER (WEDNESDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Oyingbo Ejinrin. |
| Abẹokuta | Ijoko, Iberẹkodo, Asu, Wasinmi. |
| Ibadan | Ogunjana, Lagun, Sagbẹ, Olode |
| Ijẹbu | Aiyepe, Sagamu Itaosu, Ogere Irolu Itele Ita-Iloti |
| Ijẹsha | Ijebu-Ijesha Ibodi, Ibode Kajola, Oluwa'da. |
| Ondo ati Eti Odo | Ọka Ilara, Abigi, Aiyetoro, Epẹ. |
| Egbado | Alagba Ilaro Sunwa Iboro, Jigga |
| Ogbomosho | Obada, Gambari. |
| Ekiti | Ilogbo, Oke-Aiyedun Idogun |
| Ibinni | Eko |
| Delta | |
| Igbajo | |

### ỌJỌ 'RU 13TH SEPTEMBER (THURSDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Obun Eko |
| Abẹokuta | Atan Agbado Ifo Itoku, Isabọ Ọdẹda, Ibara, Itori |
| Ibadan | Ijaiye-Orile Iressi Obada Egbẹda, Oyedeji |
| Ijẹbu | Ilishan Odogbolu, Atan, Imope Ishan, Isara, Imodi, Ajegunle |
| Ijẹsha | Esa-Oke Ilase Epe Iloba Iperindo, Imuroko, Erinmo |
| Ondo ati Eti Odo | Odojomo Igbotako Ijẹoluji Obunkekere Agirifon-Ilutitun |
| Egbado | Aiyetoro, Tata, Ilandu, Ado-Odo |
| Ogbomosho | Iressa-Du Arolu Egbẹda |
| Ekiti | Egosi Odo-Aiyedun |
| Ibinni | |
| Delta | Kokori |
| Igbajo | |

### ỌJỌ ẸTI 14TH SEPTEMBER (FRIDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Mushin. |
| Abẹokuta | Owode Otta Abalabi Sodeke Omida Ilawo Owowo Obatemi |
| Ibadan | Oja-Oje |
| Ijẹbu | Ikenne Okun-Owa Erunwon Omu Mamu |
| Ijẹsha | Ijebu-Ijesha Osu Itagu Odogbo, Iloko, Ipetu, Owode, Idoko, Ila Apa. |
| Ondo ati Eti Odo | Agbabu Igbogi Ishua Erinketa |
| Egbado | Olorunda Kajola Ilobi Eredo |
| Ogbomosho | Araromi Iregba |
| Ekiti | Erekesan |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | Iloro |

### ỌJỌ ABAMẸTA 15TH SEPTEMBER (SATURDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Agege Ikeja Ebute-Ero Ojo Ajido |
| Abẹokuta | Lafẹnwa Obada Oba Kajola Ajẹgunlẹ, Idogo, Ogunmaki |
| Ibadan | Ibuko Lalupon |
| Ijẹbu | Ibefun Atikori, Imushin, Ago-Iwoye Ijesha-Ijebu Isara, Imodi |
| Ijẹsha | Esa-Oke Iwara, Ejioro, Odo Ibokun, Esa-Odo, Ijẹda, Ikeji |
| Ondo ati Eti Odo | Igbo-Egunren Atijere Oni Ebowo. |
| Egbado | Idi-Emi Ibeshe Lasilo Atta |
| Ogbomosho | Oko |
| Ekiti | Ifaki Okemesi |
| Ibinni | Uromi |
| Delta | |
| Igbajo | |

### ỌJỌ AIKU 16TH SEPTEMBER (SUNDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Oyingbo |
| Abẹokuta | Ijoko, Iberẹkodo, Asu, Wasinmi |
| Ibadan | Olode, Ogunjana Lagun |
| Ijẹbu | Aiyepe Sagamu Ita-osu Ogere Irolu, Ita-Iloti, Itele, Oyingbo. |
| Ijẹsha | Ijebu-Ijesha Ibodi Ibode Kajola, Oluwa'da |
| Ondo ati Eti Odo | Abigi Aiyetoro Oka Ilara Epẹ |
| Egbado | Alagba Ilaro Sunwa Iboro |
| Ogbomosho | Obada Gambari |
| Ekiti | Ilogbo Oke-Aiyedun Idogun |
| Ibinni | Eke |
| Delta | |
| Igbajo | |

### ỌJỌ AJẸ 17TH SEPTEMBER (MONDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Obun-Eko |
| Abẹokuta | Atan, Agbado, Ifo, Itori, Itoku, Isabọ, Ọdẹda, Ibara. |
| Ibadan | Ijaiye-Orile Iressi Obada Egbeda Oyedeji |
| Ijẹbu | Ilishan Odogbolu, Atan, Imope Ishan, Isara, Imodi, Akẹsan |
| Ijẹsha | Ilase Epe Iloba Iperindo Imuroko, Erinmo, Esa-Oke |
| Ondo ati Eti Odo | Agirifon-Ilutitun, Odojomo, Igbotako, Ileoluji, Obunkekere. |
| Egbado | Aiyetoro Tata Ilandu Ado-Odo |
| Ogbomosho | Iressa-Du, Arolu, Egbẹda Jabata, Oke Imale |
| Ekiti | Egosi, Odo-Aiyedun |
| Ibinni | |
| Delta | Kokori |
| Igbajo | |

## ITUMỌ ALỌ

1. Oyun.
2. Oye.
3. Ogo-ile.
4. Oju.
5. Eyin ope.
6. [illegible]
7. [illegible]
8. Eti mejeji.
9. Ope.
10. Odi-eyin ope.




## CLASSIFIED ADVERTISMENTS

FUN TITA

IWE Adura 2s. 6d., Abẹla 3s. 6d. Turari Adura 2s. 6d., Abẹla Dragoni 7s. 6d. Kowe fun Iwe Isaja, Manager, Box 12, Mushin.

### IKILỌ NIPA AWỌN ALAGBAFỌ

Opolopo awon enia ni nwọn npe ara won ni Alagbafo ti nwọn si i ma n ngba aṣọ lọwọ awọn enia kakiri ti nwọn a si sa lẹhin ti nwọn ba ti gba aṣọ tan. Nipa bayi enikẹni ti o ba pe ara rẹ ni alagbafọ nilati le fi kaadi ti Ẹgbẹ awọn Alagbafọ fun un han awọn onibẹ wọn. Nigba ti a ko ri kaadi na, a le fi ri alagbafo na ti o ba gbe aṣọ wa sa lọ mu. Nitorina a pe gbogbo ọmọ ẹgbẹ yi ti Olowogbowo ati Isalẹ-Eko si ibi ipade pataki ti a o se ni Alakoro Marina ni ojo Isegun ti iṣe ọjọ kerin osu kesan odun yi, ni agogo merin irọlẹ gere. Alhaji Alarape, Akọwe Alakoso Olowogbowo.

# IJỌBA PA IBO TI NWỌN DI N'ILỌRIN RẸ

ILỌRIN.

Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kini oṣu kesan ọdun yi ni Ijọba pa ibo akoko ti awọn ti di ni Ilọrin re ninu eyi to jẹ wipe Talaka Parapọ dapọ-mọ-Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) lọ bori Ẹgbẹ Olomi (NPC). Nwọn yio si tun ibo miran di ni ọna taara, sugbọn Ijọba ko ti i f'ọjọ si i.

Eyi ni ayoriki-ẹto-ipari-ja rogbodiyan ti o ti wa ni Ilọrin lati bi ọjọmẹta yi wa nipa pe: Lẹhin ti Talaka Parapọ dapọ-mọ-Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti bori Ẹgbẹ Olomi (NPC) patapata tan ninu ibo akoko ni nwọn wa mu imoran wa pe to ba di ibo erinkeji, onisiṣẹ-mẹta (electoral College), awọn Mọgaji yio pelu awọn Talaka Parapọ to ti bori wọle, ẹde yi ni ko tẹ awọn asiwaju Ẹgbẹ Talaka Parapọ (Action Group) lorun, nitori nwọn ti mọ pe ọna eru yi ni Ẹgbẹ Olomi (NPC) ngba fi ja awọn Ẹgbẹ NEPU to ba bori ninu ibo kulẹ ni Iha Ariwa lohun.

Awọn Talaka Parapọ wa ke si Ajẹlẹ ati awọn asiwaju Ẹgbẹ Olomi (NPC) lati ba wọn mojuto ọrọ na, nitori awọn ko fẹ ki awọn Mọgaji ti nwọn ko dibo fun wa fi ẹru dapọ mọ awọn ti nwọn dibo fun ti nwọn si wọle. Awọn Minista mẹta ti Ijọba yan wa pari ija na fun wọn ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kọkanlelogbọn oṣu to kọja yi ni: — Malam Isa Kaita (Alaga), Alhaji Turikin Zaria ati Ọgbẹni Peter Achimogu.

Awọn alatunṣe ipari-ija na si ṣe ilana ẹto mẹfa silẹ fun ipari-ija na ni ibẹrẹ ipade na bayi pe:—

(1) Ki nwọn panupọ pa ibo akoko yi rẹ patapata.

(2) Ki nwọn jẹ ki awọn Mọgaji wa pelu awọn Balogun, ati pe, awọn Balogun ni yio ṣe alaga fun awọn Igbimọ Ile Idibo.

(3) Pe ibo tuntun ti nwọn yio tun di yio ṣe oju-gbangba ati ọkan-kan ọna taara.

(4) Pe ki nwọn tun ofin-ẹto idibo tuntun miran ṣe ni ọna ẹto.

(5) Pe ki nwọn jẹ ki awọn aṣoju na le si i lati mọkanlelogbọn (31) si mọkanleladọta (51) pelu awọn enia pataki ti nwọn ko ni dibo fun wọle, ati

(6) Pe bi enia adugbo kan ba ti pọ si ni ki aṣoju rẹ ti pọ si ati wipe gbogbo awọn Mọgaji to ba fẹ jẹ aṣoju Igbimọ ni lati jẹ ki nwọn dibo fun awọn wọle.

Awọn asiwaju Ẹgbẹ Ala-dapọ-mọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ati Ẹgbẹ Olomi (NPC) mejeji na si faramọ imoran ẹto iselu titun na, nwọn si tun jọ fohunṣokan nibẹ pe ki nwọn tu Ile Igbimọ Ibilẹ Ilọrin ti tẹlẹyi ka!

Eto Iwe ti alaga ipade na, Malam Isa Kaita, Minista Ariwa, Alamojuto owo ati Iṣe-Owo, ati awọn asiwaju Ẹgbẹ Oṣelu mejeji Ẹgbẹ Talaka Parapọ ati Ẹgbẹ NPC ṣe ti nwọn si fowọ si nigbati nwọn pari ipade na ni pe awọn gba imoran ẹto ti awọn Minista Ijọba Ipinlẹ Iha Ariwa mẹtẹta ṣe fun awọn.

Nwọn koi ti da ọjọ idibo na ṣugbọn ohun ti gbogbo enia fi okan si ni wipe yio di ẹhin idibo gbogbo-gboo fun Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iha Ariwa eyiti nwọn a bẹrẹ si ṣe ninu oṣu kokanla ọdun yi.

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu kesan ọdun yi ni awọn ọlọpa tun mu Ọgbẹni Abdul Kolade Joseph, akọwe-agba Ẹgbẹ Talaka Parapọ ati (Action Group) eni ti nwọn ti da silẹ lati inu tubu ni ipari oṣu keji ọdun yi pe o ṣe asiwaju fun iwode laite, e si huwa ti o le da ilu ru.

On ni eniti o ṣe ikerinlelogbọn ninu ọmọ Ẹgbẹ Talaka Parapọ na ti ọlọpa ti mu lati wa j'ẹjọ nipa rogbodiyan iwode a-ko-fẹ-a ko-gba ti nwọn fi lodi si ogbọn eru ti awọn Ẹgbẹ Olomi (NPC) fi fẹ ti awọn Mọgaji bọ arin awọn to ti wọle. Ni ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ [illegible] oṣu yi ni Ọgbẹni Joseph lọ j'ẹjọ niwaju Adajọ Kotu Kekere (Magistrate Court Ilọrin) awọn mẹtalelogbọn yoku yio lọ jẹ ẹjọ ti wọn ni Kotu Alikali.


# ẸNYIN AGBẸ ONIKOKO Ẹ RANTI



*Ja gbogbo apopo koko ti o ba bajẹ kuro ki ẹ si ma a ri wọn mọlẹ ki ẹ si ma a fun*

**'PERENOX'** TABI **'PEREPOD'**

*s'ara igi koko l'ọsẹ kẹta-kẹta*

**Ki arun korikori ma ba a gbe Koko ati Owo nyin lọ**

Ninu awọn Garawa oni iwọn ẹsun mẹrinla (14 lb) ni "PERENOX" wa
tabi
Ninu awọn Garawa oni iwọn ẹsun meji (2 lb) ni "PEREPOD" wa
Pẹlu oṣuwọn ati iwe apejuwe kekere l'ọfẹ
Didi ni awọn Garawa ogun na wa lati ri i daju pe nwọn wa ni ẹkun rẹrẹ ati pe ko ma fi le bajẹ rara.
Kii pa enia ati awọn Ẹranko l'ara bi nwọn ba lo l'ọna t'nwọn ṣe apejuwe lilo rẹ

O wa kakiri ẹka ile iṣẹ ati lọdọ awọn aṣoju
THE COOPERATIVE SUPPLY ASSOCIATION
tabi
THE UNITED AFRICA CO. LTD

Plant Protection Ltd.


## IJỌBA YAN OLORI ỌLỌPA SI ỌYỌ

ỌYỌ.

LẸNULỌLỌYI ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun yan Oga-Agba Ọlọpa kan si Ọyọ. On ni yio ma a mojuto iṣẹ awọn Ọlọpa Ibilẹ Ọyọ ati ti awọn Ọlọpa Ijọba Naijiria (The Nigeria Police Detachment) ti nwọn wa ni ilu yi.

## SERIKI IBADAN F'ẸGBẸ ALAKUKỌ SILẸ

IBADAN.

LẸNULỌLỌYI yi ni Oloye Oke Jagun Ayingun Seriki Ibadan, ẹniti iṣe igi-lẹhin-ọgba pataki kan fun Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) Ibadan, fi ẹgbẹ na silẹ pelu ọpọlọpọ ọgọrọ enia ni Ibadan. Nwọn si wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Printed and Published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 5/7, Apongbon Street, Lagos (Editorial and Advert. offices) Tels. 20855, 2058.
Fun Owo Irohin Yoruba odun kan:—Eko-sile mejo ati kobo mejo (8s. 8d.) Ilu miran ni Nigeria ati Oke-Okun sile mẹdala (15s.) Olote [illegible] Chapel Street, Lagos.

# GOMINA TU IGBIMỌ IJỌBA IPINLẸ ARIWA KA

KADUNA.

NI ọjọ Eti ti ise ọjọ kokanlelogbon osu yi ni Ọlọla Bryan Sharewood-Smith Gomina Ijọba Ipinlẹ Ariwa se ikede pe, gẹgẹbi eto iselu on tu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa mejeji ti awọn asoju ilu ati ti awọn ijoye ilu ka.

Nwọn yio si tun bẹrẹ si dibo fun awọn asoju Igbimọ miran wọle lati ọjọ Ọjọbọ ti ise ọjọ kẹdogun osu kokanla ọdun yi. Nwọn ti se eto afikun awọn asoju Igbimọ na lati adọrun si mọkanlelaadọje, nwọn si din awọn asoju pataki mẹwa ti o ti wa ninu Igbimọ na ku si marun.

Nwọn yio dibo oni-taara ninu awọn agbegbe ilu mọkandinlogun ni Ipinlẹ Ariwa ni ọjọ kẹdogun osu kokanla ọdun yi. Nwọn yio si di ibo onipele mẹta (electoral college) ni awọn agbegbe ilu yoku ni Ipinlẹ Ariwa fun ọsẹ meji nwọn o si pari rẹ ki ẹgbọn-ọjọ osu kokanla ọdun yi to to. Ni ọjọ karun osu yi ni awọn ti yio dibo l'ọna taara ati eyi ti ki i se ọna taara, a ti bẹrẹ si fi orukọ wọn silẹ, nwọn a si pari rẹ ni ọjọ keji osu kọkanla ọdun yi.

Wọnyi ni awọn agbegbe ilu ti nwọn yio fi idibo taara yan asoju kọọkan:—

Yerwa (Iha-Oke), Yerwa (Iha-Isalẹ), Nguru, Ilọrin, Offa, Okene, Ilu Kano (Gabasi), Ilu Kano (Iha-Yanma), Ilu Kano (Iha-Isalẹ), Kano Waje (mọ Sabon Gari), Katsina, Bida, Jos, Kaura Namoda, Gusau, Sokoto (Iha Yanma), Zaria ati Kaduna.

Awọn ajẹlẹ ti nwọn wa ni awọn igberiko na ni yio jẹ olori alamojuto ibo-didi na. Ẹniti yo ba dibo gbọdọ to ẹni ọdun mọkanlelogun ki o si jẹ ọmọ ilu Ijọba Gẹẹsi tabi ọmọ ilu abẹ abo Ijọba Gẹẹsi, o si gbọdọ ti gbe inu ilu ti nwọn yio dibo, fun osu mejila gbako (osu mejila le ara wọn) tabi ki o jẹ pe nwọn bi baba rẹ ninu ilu na.

# Obirin kan bi ọmọ ti ko l'ọwọ ti ko l'ẹsẹ

IBADAN.

IYANU nlanla ni o jẹ fun awọn ti o fi oju ganni "iwin ọmọ" kan ti ko ni ọwọ ti ko ni ẹsẹ, borogidi ni, ti obirin ara Inalende, Ibadan bi ni ọjọ Eti ti ise ọjọ kokanlelogbon osu ti o kọja yi (31.8.56) si ile alabiyamọ ti o wa ninu ile-itọju-alaisan, "Adeọyọ Hospital". Ẹni ọdun mẹdogbọn ni o bi "iwin-ọmọ" na eyi ti o gun ni inṣi mẹsan ti iwaju rẹ gbooro. Lẹhin isẹju diẹ ti nwọn bi i ni o ku".

Okan ninu awọn osisẹ ile-itọju-alaisan na so pe oju kansoso ti ọmọ na ni pipade ni o wa. Nwọn ti da iya "iwin" na silẹ lati ile-itọju-alaisan pe ki o ma a lọ si ile rẹ ni alafia.

Ni nkan bi osu kẹta sẹhin ni ọkan ninu ẹbi Obemla bi "ọmọ-iwin" kan ti o ni ori ẹranko ọbọ ati oju gbankogbanko meji ni oke ori na ati awọn eti keekeeke meji ti nwọn kere ju ti ọmọ enia lọ nwọn wa lori ara wọn, okun- irin tinrin ni o bo eyi ti o wa ni isalẹ.

## Ayorisi ibo-didi ni ilẹ Igbomina

ILẸ IGBOMINA.

NINU ibo akọdi (Primary Election), enia mẹrindilogoji lo wọle ni Ẹku mẹsan Oro jẹ ọmọ Ẹgbẹ Igbomina Parapọ. Bi o ti yọrisi ni wọnyi.—

Ilẹ Isin—ti Ẹgbẹ Igbomina Parapọ (E.I.P.) jẹ mejilelogoji. Ti Ẹgbẹ Northern Peoples Congress (N.P.C.) jẹ marun.

Ilẹ Sharẹ—ti Ẹgbẹ Igbomina Parapọ jẹ adọta. Ti Ẹgbẹ Northern Peoples Congress ko gba ẹyọ kan rara.

# Baba Arugbo pe iyawo rẹ lẹjọ pe o 'nya'le

ILẸṢA

OLOYE Daranijọ, Enurin Ijẹsa, ẹni ọgọrun ọdun mu ẹsun aya rẹ, Abigail Babadiya wa si iwaju adajọ Kotu Ibilẹ Ijẹsa ni ọjọ Abamẹta ti ise ọjọ kẹdogbọn osu kẹjọ ọdun yi, pe aya on na nhu iwa agbere. Aya rẹ na ni on ko jẹbi ẹsun na, o ni o di ọdun kejidilogun ti on ati Oloye na ti se l'ọkọ t'aya pọ, on si bi awọn ọmọ mẹjọ fun un, sugbọn gbogbo awọn ọmọ na ni wọn ku.

O ni nitoripe Oloye Daranijọ ti gbo ati pe ki ise ifẹ on lati wa ni aiye laini ọmọ ni on ti se lọ fẹ ọkọ miran. Adajọ na tu ẹjọ ti Oloye na pe ka. Oloye na ni on yio tun ẹjọ na pe.

## KỌLAWỌLE MARTINS F'ẸGBẸ ALAKUKỌ SILẸ

ỌYỌ.

LAIPẸ ọjọ yi ni Ọgbẹni John Kọlawọle Martins ti ise Akọwe—Eto Ẹgbẹ Alakukọ tẹlẹ-tẹlẹ ri ni Ẹku-Ọyọ, fa ẹgbọn imu ja, o ni on ko se ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) mọ on si di ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre, ninu iwe ti o fọwọ ara rẹ ko si Akọwe—Eto Ẹgbẹ Afẹnifẹre, o ni ohun ti o fa a ti on se bẹ e ni pe, oju on ti la gbangba nisisiyi pe Ẹgbẹ Alakukọ ko lẹ sin awa enia Naijiria yi de ibiti a fẹ lọ.

O ni on f'aramọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) patapata nitori eto rere, ati iwa ọmọ-luabi ati otito wọn.

## Oku ọlọmọ gẹgẹ lao gbe

OGBOMOSO.

NI deede agogo meji ọsan ọjọ Isẹgun ti ise ọjọ kẹrindinlọgbọn osu kẹfa ọdun yi ni iya oninure Ogunronkẹ Abeo jalaisi ni ile Balẹ Mayin isalẹ Ilogbo, Ogbomoso. Ẹni adọrun ọdun ni ise. O si fi ọmọ meji Ọgbẹni Raji Okejinmi ati Samuel Okeyode s'aiye lọ.

Awọn ọmọ oloku na na owo, nwọn si na'ra, nwọn fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ wọn lọrun. Alufa Raji Adigun, ọrẹ ọmọ oloku paapa na owo ni ibi isinku iya oninure na.

Ninu awọn ti o wa nibi asẹyẹ isinku na ni Ọlọla Sam Ogundipe, Alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ogbomoso awọn Ọgbẹni R. A. Ilabalẹla, M. B Adenju, J. O. Oluokun, Oye Oyewole, J. T. K. Lanipẹkun, Samuel Ladele ati awọn Ẹgbẹ Tẹpamọsẹ, Irepodun ati Ẹmilere. Ọgbẹni ayantebo ati Ayantola fi ilu wọn dabira nibi asẹyẹ na.

Ọlọrun ko fi ori jin iya o



Ọlọla John Macpherson, Gomina-Agba akọkọ fun Naijiria wa nibi ẹyẹ kan ile Ẹka National Bank Lọndọnu na. On ni o wa ni ipo kẹrin lati ọwọ ọtun.











IPARA TO DARA JULỌ

MENTHOLATUM


# NATIONAL BANK ṢI ẸKA ILE IṢẸ SI LỌNDỌNU








FUN AGBARA

NIBI IṢE L'OSAN

FUN ALAFIA

NINU ISIMI ATI ERE



FUN ILERA AWỌN EBI, LO

HOMMEL'S

HÆMATOGEN




# ỌGBẸNI SNELL BẸ ỌBA ALAKE WO





## Ọgbeni I. B. Ṣode bẹ Olọtu wo

## Ikomọ ọmọ Salami Fagebọ dun



E MA A KA IWE IROH N YORUBA NIGBAGBOGBO


AWON OGBOLOGBO

(SCRAP)

OJE (LEAD)

IDE (BRASS)

BABA (COPPER)

AWỌN ALOKU IRIN

ERO MOTO (RADIATORS)

PAANU AYO (ALLUMINIUM)

JE OWO

Ko wọn wa ta fun

BUCK (NIGERIA) LTD.,

2, AERODROME ROAD, APAPA.

TELEPHONE:

84477.

Fun ilera daradara




Wara ti o le gbẹkẹle ni



KLIM

Wara ti o darajulo fun gbogbo awọn ọlọmọde

# Nasser gba lati ba awọn Ikọ-Agbaiye ṣe ipade

CAIRO-EGYPT.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu kẹjọ ọdun yi ni Ọgbẹni Colonel Abdel Nasser ti iṣe Alakoso Ijọba Ilu Egypti gba lati ba awọn Ikọ marun ti Igbimọ awọn orilẹ-ede yan lati ba a ṣe ipade lori ipinnu wọn lori odo itọ Suez (Suez Canal).

Ninu awọn orilẹ-ede mejilelogun ti o lọ ṣe ipade ni Lọndọnu lori eto odo itọ yi, awọn mẹtadilogun ni o f'aramọ ipinnu ti nwọn fẹ fi siwaju Colonel Abdel Nasser yi, ipinnu wọn na ti nwọn jijọ ṣaṣaro le lori nipe ki odo itọ Suez wa ni abẹ itọju awọn alakoso orilẹ-ede.

Ẹniti yio ṣe Alaga Igbimọ Apero na ni olori awọn Ikọ marun na Ọgbẹni Robert Menzies Alakoso Ijọba Australia, ibiti nwọn si ni ero lati ṣe ipade na ni ilu Geneva tabi ni Romu. Bi nwọn ba dẹ ti yanju ọrọ na si ẹ o ma a gbọ.

## Ọkọ Reluwe tẹ enia pa

IBADAN.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadilọgbọn oṣu Kẹjọ ọdun yi ni ọkọ Reluwe tẹ ọdọmọkunrin kan, ẹni ọdun mejidilọgbọn ti oruko rẹ njẹ Isaiah Adeniran, ara ilu Ondo, ti o ngbe Opopo Amunigun ni Ibadan pa.

A gbọ wipe Adeniran wa pade ana rẹ kan ti o mba ọkọ Kano rekọja lọ s'Eko ni, ṣugbọn ki ọkọ to de o ti sunlọ si ori pepele lẹba ọna-ọkọ, ọkọ si tẹ ẹ ni ẹsẹ fọ tu u tu u. Ki ẹmi rẹ to bọ nigbati nwọn ngbe e lọ si ọsibito lo yara tete so oruko re, ilu rẹ ati iye ti o ni ni Banki fun awọn to sure wa ṣe ajo rẹ.

## Okesanya ati Omirin ṣe Ijade Igbeyawo

TESON IJOKO.

OPỌLỌPỌ awọn enia gidi ni nwọn ba awọn Ọgbẹni I. O. Okesanya ti nṣiṣẹ ni Teṣoun Ifọ ati I. A. Omirin ati awọn iyawo wọn titun ṣe ẹye ijade iyawo na, ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun osu kẹfa ọdun yi, ni Ijọ "Ebenezer Church". Teṣoun Ijoko. Alufa S. O. Akinde ni o ṣe akanṣe isin ijade awọn iyawo na. awọn alufa E. A. Adelẹyẹ ati J. S. Fasunvi ni o ran an lọwọ.

Awọn ọkọ iyawo mejeji na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun. Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu wọn ni awọn Ọgbẹni A. K. Ṣoetan, E. A. Adeṣina, S. A. Phillips; awọn ẹgbẹ Y. M. C. A. Ifẹlodun, Ifẹdapọ ati Ireti. Ire a kari o.

## AWỌN ORẸ ṢẸYẸ IDAGBERE FUN ỌBADASHA

ARIGIDI.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ karun oṣu kẹjọ ọdun yi ni awọn Ọgbẹni Enoch Adedeji, akọwe Ile Ifiweranṣẹ, ati Lawrence Omoke, ọga iṣẹ oju ọna ti ilu Arigidi, ṣe aṣeyẹ idagbere fun Ọgbẹni Emmanuel Ọbadasha, akọwe Ẹgbẹ Agbe (Co-operative Secretary) ti iṣe ngbe lọ kuro ni ilu Arigidi.

Alaga aṣeyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni Amos Awolu awọn isọngbe rẹ ni awọn Ọgbẹni:—Jaiyeọla, Ilepa ati L. Okafor, aṣeyẹ na bẹrẹ ni deede agogo meji ọsan, alaga sọ orişirişi ọrọ iwuri nipa iṣẹ rere ati iwa rere Ọgbẹni Ọbadasha ati fun ilọsiwaju Ẹgbẹ Agbẹ ti o ba wa sibẹ, Ọgbẹni Ọbadasha na si dupẹ lọwọ gbogbo wọn fun ifẹ, nwọn si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni:—Samuel Adefẹmi, Aibinu, Adelẹgan C.P.M.S. H. Ọlagunju Ilẹpa, Okunọla Agun, Moses Ogokunle Apeloye, Michael Ọlọruntọba, Ọlatawura ati Ezekiel Adeosi.

## ỌWỌ ỌLỌPA TẸ AWỌN-AṢẸWO

IBINNI.

OGORUN awọn obirin oniṣẹ-aṣẹwo ni ọwọ awọn ọlọpa tẹ ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kinni oṣu yi. Ijọba pa laṣẹ fun won pe ki nwọn fi ilu Ibinni silẹ larin ọjọ meje bibẹkọ nwọn yio ba wọn ṣe ẹjọ. Eyi ni o di ẹlẹkẹta ti ọwọ awọn ọlọpa ntẹ awọn obinrin aṣẹwo ninu ilu yi ni ọdun yi.













## Classified Advertisement

READY FOR SALE

Alaiik ko ma a ba wa gbe 1957 Calendar 3s. Doz. Postage extra; apply I. Sho. Bankole, 34 Idita Street, Lagos.

